## Asotele Oro

A gbo irohin lenu awon alasotele wipe, Omi yio ya wo ilu Eko lati ona okun wa ati pelu, ojo ojo meje kan yio ro. Sugbon lehin ekun mi, Owo yio wo ilu wa.

Oluwa gba lowo nru omi okun, ati arọida ojo Amin.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

## Akiyesi Pataki

A fi..e yi s e ilede si awon Asoju iwe irohin Eleti Ofe kakiri agbaiye wipe, enkeni ti ko ba fi owo ti o ti je raase ..., no pe lejo, ako si ni fi ..e irohin ranse si en be mọ.

VOL. XI No. 634. LAGOS, SATURDAY, JULY, 25—JULY 31, 1959. KOBO MEJI (2d.)


# Ibosi Oro o! Ibosi Etu Oloro! Ibosi Faranse!!

EKO Gbogbo ilu enia dudu kakiri agbaiye l'o nkegbe ibosi Faranse, lori etu Oloro ti nwon se eto lati danwo ni ile oken yanrin ti a npe ni Sahara, sugbon bi gbogbo awon ilu wonyi ti nkegbe rara to yi, awon ilu alawo funfun nse adonkia si oro na ni.

Akowe agba ilu Gesi so wipe awon Faranse ni etu oloro yi ko ni se ipalara kankan fun wa. Asoju Ijoba Faranse tilu Eko, ewe, so wipe ko si eyiti o gun on nibe.

Gbogbo awon oselu wa ni o nkegbe to o pe Ijoba orile-ede kakiri agbaiye wipe ki won gba wa lowo etu oloro ti ijoba Faranse fe fi da ijogbon sile wa yi.

Oro yi wa ku s'owo adura, nitoripe awa enia dudu ko ni ohun ija kankan lowo.

**Ibosi Oro, Ibosi etu oloro Ibosi Ijoba Faranse.**

## OKUNRIN KAN PA OBINRIN BO ORIṢA RE

IBADAN. Okunrin kan rojo ni iwaju adajo nilu Ibadan wipe orisa on gba eje enia, nitorina ni on se pa obinrin yi lati fi bo orisa na. Okunrin na gboju gboiya o tun so fun adajo wipe enia mewa ni on fe pa bo orisa na, eni kansoso ni on sese pa o ku enia mesan.

Orukoobinrin ti nwon pa na a ma je, Okeronke Ajeigbe oruko apania na ni Ogunbiyi Ishola. Okunrin apania na tan Ajeigbe de ibiti enia ko le ri won, o si la irin to wuwo kan mo lori, o si bere si fi eje ara obinrin na kun oju re. Oro ejo na si wa ni kawo awon olopa, nwon si nwadi siwaju.

## OKOTIE EBOH PADA DE SILU LONDON



**Eniti a nwo yi ni Oloye F.S. Okotie Eboh, eni ti** o ti fi igba kan rin irin ajo lo be ile awon Koraa (Lebannon) ile Pakistan, ile India ati ile awon omo Israel (Israeli) wo.

Ohun ti o lo be awon ilu nwonyi wo fun ni wipe, bi yio ba ri iranlowo owo ati awon ti o mo nipa ise ero lati ilu okere wa sile Nigeria.

## EDEKOYEDE BE SILE LARIN AWON ELERAN

ABEOKUTA. Oloye Abinteye Coker ni a gbo wipe, o se iwe si kotu, o fi mbere ase lodo Adajo, ki o ba won yo Ogbeni kan ti o nje Bello A. Olatunji kuro larin awon egbe eleran, ti o nta eran ni Sabo, Abeokuta.

Alhaji Gambo so niwaju adajo wipe, Oba awon Hausa ni Abeokuta lo fun won ni ile ibiti nwon gbe nta eran ni Sabo, ati wipe Ogbeni Bello ti a wi yi, ko si ninu awon egbe eleran.

Awon igbimo egbe eleran wa se ipinnu wipe, enikeni ti ko ba ni oruko ninu iwe egbe wa, ko gbodo ta oja larin wa mo. Nwon si sogba yi ibiti nwon nta eran ka, sugbon Bello lo fi agbara ati tulasi ja ogba na o si nta eran tire larin wa.

(Koiti pari).


## THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches Througout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE

1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303 — Cables & Telegrams Nathaniger London.
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

## LAGOS RACE CLUB

### AUGUST MEETING

Saturdays 1st, 8th, 15th, 22nd and 29th August, 1959.
Racing Starts at 2.45 p.m. each day of the Meeting

DECLARTION

To be made at the Secretary's Office between the hours of 5 p.m. and 6 p.m. on Fridays 31st July, 7th, 14th, 21st and 28th August, 1959.

ADMISSION TICKETS (ADVANCE PURCHASE)

ADMISSION TICKETS for the Meeting can be purchased in advance at the Secretary's Office, at the Paddock between the hours of 5 and 6 p.m. on the day preceding each day of the Meeting.

ADMISSION : 5/- per day including Entertainment Tax.

CHILDREN

No Children under the age of 14 years will be permitted to enter the Members Enclosure.

## EKO SI LONDON DI IRIN OJỌ KAN

EKO. Latete kọse nigbati ọkọ ofurufu koiti de, irin ajo ninu ọkọ oyinbo jẹ oṣu mẹta fun ẹgbanji buso. Nitori pe lati Eko si London jẹ 4,000 buso. Iyẹn niwọn ọdun 1912.

Nigbati o di ọdun 1920 irin ajo silu Oyinbo di oṣu kan. Ni ọdun 1932, o di ọsẹ mẹta. Ninu ọdun 1940 lo di irin ọsẹ meji.

Ni ọdun 1930, ni ọkọ ofurufu de ti nwọn nwa ọna kukuru fun irin ajo na. Nigbati o ṣe ni nwọn ri ọna kukoru kan ti nwọn fi nrin ilu Oyinbo ni ọjọ mẹta.

Ṣugbọn awọn Oyinbo ọlọkọ ofurufu (B.O.A.C.) nfi ye wa pe ọkọ ofurufu wọn ti nwọn npe ni Britannia, yio kuro ni Eko ni owurọ, iwọ yio si de ilu Oyinbo ni aṣalẹ. Bayi ni yio rin irin ajo na.

Yio kuro ni Eko ni agogo mẹjọ owurọ, yio de Barcelona yio si kuro ni Barcelona ni agogo marun koja yio si gunlẹ si ibudo ọkọ ofurufu ni London ni agogo mẹjọ alẹ.

Iyẹn ni pe, bi a ba mu ẹkọ arọ nilu Eko, ao jẹun alẹ nilu Oyinbo.

## Oko Ogun Fun Ile Nigeria Mbo

ENGLAND. Agbọ irohin wipe Ijọba Gẹsi fi ọkọ ogun kekere kan ti o ma nṣe ọdẹ awọn ọkọ abẹ omi (U Boat) ati ọkọ igbaja ayara-bi-aṣa kan ta awọn ọmọ ogun oju omi ti ilẹ Nigeria lọrẹ.

Malam Abudu Maliki ti o jẹ aṣoju ilẹ Nigeria sọ nigbati nwọn fi oko na le lowo wipe, oba obinrin ti gba lati ma pe gbogbo soja oju omi ti o ba jẹ ti Nigeria ni Royal Nigeria Navy (R.N.N.) Oruko oko na papaa njẹ H. M. S Nigeria.

Iyafin Oyinkan Abayomi lo so oruko oko na ni Nigeria, yio bẹrẹ irin ajo rẹ wa si Eko ni ojo Tuesday 6th oṣu October 1959.


Kere o !

A ni orisirisi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS MEDICINE STORES
7 Egerton Road Lagos


## OGBORI OLORI KALẸ LORUN GANGAN

A gbo irohin wipe okunrin kan lo hu oku kan jade ninu sare, o wa gbe lo sile-onile, o si lo bo mole nibe.

Lehin ti o se ise buburu yi tan o lo si odo awon olopa, o fun won ni irohin wipe okunrin ti o ni ile yi bo odidi ori enia mole ninu ile re a ko si mo gegebi yio tio se ati ibiti o ti ri.

Awon olopa dide lo ba Okunrin onile na wipe nibo lo gbe ti ri ori enia ti o bo molẹ?

Bale ile na sọ bamubamu pe on ko ni mimo ohun ti o jo bẹ. Ọdaran to hu oku dahun wipe iro lo pa eyiti o ri molẹ nko?.

Nigbati awon olopa ri oye pe iro ni awon pa mọ Bale ile na, ni awon olopa ba fi okunrin na sun ẹsun wipe o wa fun awon olopa ni irohin ti ko nse otitọ. Adajọ ti yẹ ẹjọ re sinu oṣu August.


OGUN ITAJA POLOWO ỌJA RẸ SINU IWE IROHIN ELETI - ỌFẸ



ARA-O-LIN - IPARA ATATA




ARA-O-LIN je ipara ti o gbamuse. O tayọ gbogbo irufẹ egbogi bẹẹ ti o ba l'ọja. O dara fun lakuregbe, ẹgbedidan, aranlatanlatan, ẹhin-didun, ibaradi-ṣiṣe, arinka-inu-egun ati apa tabi ẹsẹ rọ, ẹfọri, tulu, otutu-aiya, otutu-agbari, ikun-didinu, ọrun-didun ati orisirisi aisan kungẹkungẹ bawọnni. Nitori werewere ti o nta, awọn Yoruba npe e ni "ATA", Ibo npe e ni "OSE" Hausa si npe e ni "BORỌKONU". Dan igo kan wo ni 2s. 6d. (ọbọ l'owo-ọkọ) lati mọ bi o ti ri.Kọpẹmani ni.

The Ẹgba Trading Aradan Stores,
16 Denton Bridge St., P. O. Box 2, Abeokuta-Mọkin.







## ẸLẸWỌN KAN TUN GBA IDAJỌ ỌDUN MẸRIN KUN ẸWỌN RẸ.

IBADAN. Ọkunrin gbajumo kan ara ilu Iwo ti orukọ rẹ njẹ Wusamọtu ni a gbo wipe, o se aṣemaṣe kan ti nwon si ju si ẹwon. Ninu ẹwon yi lo wa ti nwon fi tun ranṣẹ pe e lati wa jẹ ẹjo ninu kotu ọdaran ni Ibadan.

Nigbati nwon nsọrọ na lọ, nwon da oruko Wusamọtu pe o mbẹ ninu awon ti o lọ ji £674 owo awon Igbimọ Iwo, awon ọlopa sọ fun adajo wipe onibara won ni, ki adajo mu u daradara.

Adajo dahun pe ki o lọ si ẹwon odun merin, ki o fi kun eyiti o ti nlo bo, ni Wusamotu ba jẹ ara ṣawu.

## ỌKUNRIN KAN DIJỌGBỌN SI ALADUGBO L'ỌRUN

Ọkunrin ti o njẹ Ubagala ọmọ ọdun mẹtadilọgbọn lo lọ ji ewurẹ ẹniti awọn npe ni Musa Agnika gbe ki ọwọ ọlọpa to tẹ.

Awọn ọlọpa sọ fun adajọ wipe ọkunrin ole yi ni alalẹ ni o ma nlo sile onile lati lọ gbe wọn ni ẹran pẹlupẹlu. o ti di ijọgbọn si awọn enia rẹ ati awọn aladugbo rẹ l'ọrun.

Adajọ kotu Nasarawa sọ fun ole na pe, nigbati iwọ koiti gbọn nisisiyi, nigbawo ni iwọ yio gbọn.

Nitorina adajọ ni ki o lọ si ẹwọn oṣu mejidilogun ki nwọn si na ni ẹgba mejila.

# Omobinrin To Bori Ninu Ere Bolu



Omobinrin kan ti o nje Christine Truman on lo joko lori aga lowo otun pelu arabinrin re ti o nje Nell ninu ile re ni Woodford Green, ni ilu Essex. On lo ba won lo sere bolu afowogba (Tennis) nilu Faranse ti o si yege bowa sile

## Akowe Kotu Lo Gbewa Ni Bornu

EKO Akowe Post Office kan ti oruko re nje A. Akinbgbule, ti o ti nsese ninu ogba Post Office ri ti a gbo wipe o se owo fere ti nwon si laa mo inu ewon ni a gbo wipe o tun se asemase o lo yi iwe o fi oruko ara re gba owo olowo sile metadilogun, nwon si ma lati inu ogba ewon wa je ejo miran.

Koiti bo kuro ninu ejo kan, ti o fi tun lo fi ara gba ewa osu mesan miran BORNU. Okunrin kan ti oruko re nje Aba Kura ti o nse akowe kotu nile Boronu, ni awon Olopa ramu fun esun wipe, o ji owo Ijoba Poun marun ati sile marun.

Nigbati ejo re de iwaju Alikali kekere nile Boronu, o jebi esun ole, adajo ni ki o lo si ewon, sugbon o taku wipe niti on, on ko jebi o gbe ejo lo siwaju Alikali agba ni Medugari.

Agbase gbo bo, Alikali agba na so pe akowe kotu na jebi esun ole, nitorina ki o lo gbewa osu mefa.

## DR ENDELAY NSE IKILO FUN ARA ILE KAMARUN

KAMARUN. Dr. Endeley Olori Alako fun ile igbimo (Assembly) ni agbegbe isale ile Kameruu nse ikilo fun awon ara re wipe, enyin ara ilu Bera bi e ba gba lati jara kuro l'ara ile Nigeria, bahanle iya ni yio je nyin, ki e si se akiyesi awon ohun ti o nsele ni agbegbe ile Kameruu ti o mbe labe Faranse, awon baru ji ogun Idahomi lo.

Nitorina, mo fi eyi fa enyin ara ile leti wipe, ki e je ara kanna pe pelu ile Nigeria ni ohun ti ole se nyin ni aofaui. Nitoripe ijoba awon bowo fun ofin.

## Adedoyin Lo Ko Ise Ero Gbohungbohun



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni L. D. Adams ti o je okan ninu awon oluko ti o nko won ni ise ero gbohungbohun (Radio) on ni a nwo ti o duro ti o si fi okan han Ogbeni O. T. Adedoyin ara ilu Shagamu ni Remo.

Adedoyin pada lo dulo ti o tenba nwaju ona re.

## E Fi Oro yi Yemi o

Olotu,

Gba mi laye lati se ibere yi wo lodo awon Igbomina, ki nwon fun wa lesi re.

A gbo lenu awon opolo wipe lati otile Illa Orangun ni ogun Ilorin ti fon won ka ti olaiyabaku won si lo te ilu do, bi Oke-Ode, Omupo, Omu-aran, Igbaja, Sare, Ajasse, Ipo ati awon ilu bawonni.

A si tun ngbo ti awon Yoruba ma nki awon ara ile Igbomina kan ni Tanmagayi bi egba a oke omo kesin-loro. Nwon ni awon Tapa ni nwon nki be. Bida, Kotongora, Minna Bare ati Pateji ni a npe nje Tapa.

Bakanna ni a gbo pe bi o ba yo si awon Fulani ti Ilorin, ara Oke Ora kan ko gbagun sola-bi wa ba Yoruba jagun ri. Ba ato ni awon Igbomina se di tape ti awon Ti nki won ni ofa bi egbesun oko bi egbefa, Tanmagayi bi egba a oke omo Kesin loro?

Oro na ru mi loju, e dakun e lanu fove oro na, nitori ki a ma ba gbagbe itan lehin ola.

Emi ni, Omo College.

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
38, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - ỌFE LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL XI. NO 634 SATURDAY JULY 25 - JULY 31, 1959


## Agbajo Owo L'afi Nsoiya

Awọn Yoruba mọnimọni ti ni ọgbọn ati ero ti o pẹye ki nwọn to sọ wipe, Owe ni ẹsin ọrọ, bi ọrọ ba sọnu, owe ni a fi nwa" bẹgẹgẹ ni owe ti a fi ṣe akọle oke wosika wa ọsẹ yi fun ẹnyin ọkawe wa.

Irohin kan wa lati ilu Liberia, ilu awọn Kurumọ, wipe awọn aṣiwaju oṣelu ilẹ Liberia, ti Ghana ati ti Guinea ti f'ohun-ṣọkan wipe ki gbogbo orilẹ - ede enia dudu ti o ba ti gba ominira tabi eyiti o ba ti nf'oju s'ọna fun ati gba ominira jumọ ṣe ipade apero nla kan po ninu odun 1960 lati ṣe idasilẹ ajumọ-ṣepọ awọn ilẹ enia dudu ti o di ominira.

Iru ero ti awọn ogunna gbongbo mẹta gba gẹgẹbi imoran yi, jẹ ero ti o dara loju tiwa ti o si mu ọgbọn dani.

Nitori eyi ni ohun ti o mu wa fi owe oke wosika wa yi ṣe esin orọ wa wipe "Agbajọ ọwọ ni a fi nsọiya" iyẹn ni pe gbogbo ohun ti a ba pejọ pọ ṣe nilati yọri si rere.

Nitorina, ẹnyin ọmọ iya wa, ẹ jẹki a jọwọ o, ohun ti a ba jọwo l'o ngun.






## Awon Ogunna Gbomgbo Meji



Awọn orẹ meji ti a nwo yi ni Prime Minister ilu Gẹsi, Sir Harold Macmillan ati Baba ẹgbẹ awọn oṣelu ilẹ Amẹrika, Ọgbẹni Eisenhower. Nwon ya aworan yi nigbati Macmillan lo ba awọn ara ilẹ Kanada soro kan. Alagba na so pe oro ti on titori rẹ lo silẹ Kanada dara pupo.

## Afese Kan Pa meje

(Apa 7)

**Lẹhin ti Afẹṣẹ pa meje ti fi aake ọwọ rẹ ge iwo kanṣọṣo ti o mbẹ ni agbara ẹranko na tan, okun ti o ti koko so mo o lorun wa** dabi enipe Afẹṣẹ pa meje lo so mo ara igi.

O pada sodo ọba pẹlu ẹrin lẹnu rẹ, o wipe, Ọba ranṣẹ lo ki nwon lo yinbon pa ẹranko na, nitoripe mo ti mu u, mo si ti gba agbara ija rẹ kuro. Inu gbogbo enia dun, nwon ho ge-e-e Ọba ran awon jagun-jagun mẹfa lọ, nwon si pa ẹranko na, nwon ru u wa silu, oba fi se ase

L'alẹ ojo na, oba pe apejo kan lati fi yẹ Afẹṣẹ pa meje si fun iṣẹ ribiribi ti o ti ṣe fun ilu na. Ọba na yẹsi, o yin i, o dupẹ fun, o wa fi owe kekere yi pari ọrọ rẹ wipe, "Agbatan ni a ngba olẹ, bi a ba da aso fun olẹ a si pa laro." Nitorina emi ọba ati awon Ijoye ati gbogbo awon ọke meje enia ti o ngbe inu ilu yi fi eyi kesi Afẹṣẹ-pa meje wipe ki o jọwọ ba wa ṣe asepari ohun ti o nda-wa lamu nilu nitorina idanwo na ku ọkan.

Nigbati Afẹṣẹ-pa-meje ri iru ọla ati iyi ti nwọn fi yẹ on si bayi, ori re si wule, o si dahun gẹgẹbi akoni enia wipe, sibẹsibẹ ewu si mbẹ nibiti Afẹṣẹ-pa-meje gbe wa, mo ti ba Omiran olori meje ja, mo pa a, mo ba ere ata oṣumare ja mo paku yanyan, mo ba Ira oniwo kan ja, mo muso gegebi aguntan. Wi fun mi nibo ni ewu na gbe wa ?.

Ọba dahun pe ni apa Ila-Orun yi, ni ẹranko buruku kan ma nda enia lona, a si ma pa won jẹ. Eyi ni ewu kanṣoṣo ti o ku Mo si fẹ ki o da Afẹṣe-pa meje loju wipe bi o ba le yanju ẹranko buruku na kuro lona fun mi, laiṣe ẹtẹ lẹṣọ, omo mi obinrin yio ba ọ de ilu rẹ.

Afẹṣe pa meje tun dide lati sọro, o wipe 'ohun ti e wi yi mo ti gbo ṣugbon mo fẹ ki ẹ ṣe itanlowo kan fun mi. Gbogbo enia si dahun pe wi ki a gbo, awa yio ṣe el

L'osẹ ti o mbọ ẹ o gbo bi Afẹṣẹ-pa-meje ti pari iṣẹ rẹ na ti o si gbe omoba niyawo. E ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ.

# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

## WOOD POLES

Tenders are invited from responsible factors for the supply of Impregnated Wood Poles strictly in accordance with BSS. 1990.

Initially, the following quantities of Wood Poles will be required :

500 - 16 ft. long drilled with 2 holes
1.500 - 24 ft. long drilled with 3 holes
1.500 - 28 ft. long drilled with 5 holes
500 - 33 ft long drilled with 9 holes

On payment of a deposit of £5 tender documents Comprising tender, specifications of the contract, etc., may be obtained from The Secretary, Electricity Corporation of Nigeria, Electricity Headquarters, 13, Broad Street, Private Mail Bag 2030, Lagos.

**Each tender must be enclosed in a sealed envelope marked "Confidential - Tender for Supply of Wood Poles" and must be received at the Office of the Secretary not later than noon on Saturday, 22nd August 1959. Tenders received in any other manner will not be considered.**

**On receipt of a bona fide tender the £5 deposits will be refunded. The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any tender.**

**Further information concerning this contract may be obtained on application to the Chief Electrical Engineer at this Headquarters.**

**Arthur Faul**

Secretary to the Corporation

## OMO ENIA DUDU YE OMOBA SI



Ọmọ enia dudu ilẹ Nigeria kan ti nwọn npe ni Grace Odili, ni o fi ododo orişirişi şe nyẹsi fun ọmọba obinrin kan ti o njẹ Duchess of Northumberland nigbati ọmoba na wa şi ọja Basa kan nilu Oyinbo fun idagbasoke egbẹ Y. W. C. A. ni adugbo ti nwọn pe ni Newcastle.

### DEVELOPMENT FINANCE COMPANY FOR NIGERIA

A further important step towards the establishment of the Investment Company of Nigeria Ltd. took place on 16th July, 1959. The steering Committee, whose appointment was announced on 1st July, held its first meeting under the chairmanship of Mr. J.H. Belsham.

The Committee considered drafts of the formation papers of the Company and they took a number of important decisions on the constitution of the new Company, the procedure for its formation and the manner of securing capital subscriptions.

They were assisted in their deliberations by Mr. B. Berkoff, a representative of Commonwealth Development Finance Company Ltd., who flew to Lagos from London for the meeting.

Solicitors in Lagos and London will now revise the formation papers in accordance with the instructions of the steering Committee so that the Company may be registered and commence business at an early date.



AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.

## Owe Ile Yoruba

1. Ko dunmi, ko 'dun' mi agbalagba mbu opa lemefa nitori iyan ana.
2. Eni ba fi oju agbara wo Kuset, omi yio gbe lo.
3. Aiye ko ni pekun, e jeka aje papo ki nto ma lo.
4. Erin tabe mgbo, ti o nse gbo ajanaku mbe l'odan, to iwo odan ajanaku ti a ri ti a di se eru, o sile, erin koja ko ba ibe lo.
5. Ero ni Babalawo npa, ko ri ifa ri, iro ni Isegun npa, ko ri ogun, awon Abegungun ko ri egungun ri bena awon Aborisa ko ri orisa.
6. Olorugbe ko jewo, atanije ni olorun eke tan ni si ijaekun o fi orun sise si apo eni.
7. Eke ni yio pa eleke, odale a si pa odale awon lo da ifa fun Amotunkun-sole ti o wipe, oju oba aiye k o ti on. Bi oba aiye ko ri o oju oba orun ko ha nwo hi !.
8. Eni Oforo ni yio pa oforo, nitori nigbati oforo jeun yo tan o ni gbogbo ile on kun so so so.
9. Aiye ko lora.

## IYE AWON ODARAN TO WO EWON LODUN 1957-58 NI NIGERIA

Ninu odun 1957-58, o le ni oke meji awon arufin ti awon gbe ju si ewon. ara ile Ibo to wa ninu won je 15,280. Awon Yoruba to mbe nibe je 7,019. Awon Hausa je 4, 121. Iye awon Ibibio 3,922. Awon ara ile Kamerou 2,008.

Awon obinrin to je elewon kakiri ile Nigeria je 2,413. Ibo je 1,203, Ibiobio 377, Yoruba je 319, awon Hausa je 135, Ijo je 102.

Awon ajeji ti o mbe ninu ewon nisisiyi, ni awon Oyinbo 21, Kuruman 55, Ghana 61, Saro 29. Lodun 1956-57 iye awon odaran to wo ewon je 38,096, eyi fihan pe nse ni awon enia tunbo nri eri ninu iwa odaran.

Ijoba woye wipe gegebi awon odaran na ti npou siwaju yi ogba ewon ti o wa ni Broad Street ko ni gbaye lobe mo, nitorina nwon lo ko ile elewon nla kan si abule ti awon npe ni Kiri-kiri ni apa eti osa, niwaju Apapa die.

## Om Yoruba To Lo Ko Ise Ero Nilu Oyinbo



Enilti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni D. A. O. Amao ti o je omo ile Yoruba lasiko ti o wa ni Loughborogh College nibiti o gbe nko ise ero, on lo mu ero dani ti a nwo iy pelu omo akeko ara ile Holland kan ti o nko ohun ti Amao ba so fun sile.

## Inland Waterways Department

NOTICE NO. 22

LAGOS/WARRI CREEK MAIL SERVICE

It is notified for general Information that the above service will again be extended to TROFANI commencing with the voyage leaving Lagos on the 1st August 1959 and until further notice.

C. ATKINSON
Director,
Inland Waterway Department

ELETI-OFE D'ARABA

## AWON OYINBO ONISOWO U.A.C YEWO NINU KOKO RIRA

EKO - Awon Oyinbo Onisowo U.A.C. se ikede wipe awon yowo yese kuro ninu Koko tabi ekuro rira ni awon ilu bi marun nitoripe awon Onisowo enia ti e ti gba iwe ase fun Koko ati ekuro rira ni apa ihahin ti po to.

Ikede na so wipe awon oyinbo Onisowo U.A.C. yi, yio mojuto awon oja titun miran ti awon yio ma se idagbasoke awon oja be. Ati wipe awon yio se iranlowo fun Onisowo Koko ati ekuro ti agbara won ti rele nipa oja rira fun asiko oja ti o mbo yi.

Awon ilu ti awon Oyinbo Onisowo U.A.C ti yowo na ni, Eko, Ibadan Ijebu-Ode Shagamu ati Abeokuta.

## OLUTOJU SOBU NTI OJU LATI WIPE OWO OJA SONU

Okunrin kan, omo ogoji odun ti o nje Ben, ti o nse ise alabojuto nile ise oyinbo ti o nta masini (SingerSewing Machine Co.) so niwaju adajo pe lowuro ojo kan nilu Ibadan ti on de sobu ni nwon ji adotalerugba poun lo lowo on ninu (Bank) ile ifowopamo si, sugbon oju nti on ko jeki on le so fun enikeni, on si ni aniyan lati san owo na pada sibe.

Ben ti a wi yi ogun esun ni awon olopa mba ro wipe o lo jibiti fun onise re o si tun ji won ni owo ti o to £1,142.

Bi on ti je alabojuto fun awon ti o nta oja sibe on ko ni ile beni on ko ra ile. Nigbamiran on a ma rin irin ajo. Nigbakan ti on lo si ajo, ki on to pada de, nwon ti paro kokoro ilekun. Bi kokoro kan ti mbe lowo on ekeji re mbe lodo Iyafin Elizabeth.

Ejo na si mbe ni koto.

E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LOSOSE
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

## ANGẸLI ITỌLỌ KO NṢE BALOGUN ADAMU

Olotu,

Jọwọ gba mi laye ninu iwe rẹ Oloyinmọmọ lati fi ye awọn ara Ilọrin ati awọn Igbomina ti nwọn si ni igbagbọ wipe angeli Itọlọ ti nwọn gbe lọ si Oke-Suna wipe Balogun Adamu ni nwọn ya aworan rẹ sibẹ.

A ṣe abere ẹhin wo lọwọ wọn pe, bawo le ti ṣe jẹ bẹ? Nwon dahun pe, Balogun Adamu lo ba oyinbo ja ogun ati oku ati aye rẹ ati ẹṣin rẹ ẹnikan ko ri mọ titi di oni.

ṣamoṣamo awọn oyinbo lo ki mọlẹ nwọn si lo ya aworan rẹ gẹgẹbi Balogun Adamu ti ṣe nmura ogun, bẹ gẹgẹ ni Angẹli Itolo mura ti a nwo.

Mo fẹ fi ye awon eniа wa wipe aworan ti nwon pe ni Balogun Adamu ko nṣe Adamu rara, bikoṣe Mọlaika Mikaila nínu imura ogun rẹ pẹlu Satani, Balogun Adamu ti ku o si ti ba ogun lọ.

## Ole Ji Taya Ese Moto

ABẸOKUTA. Ọdomokunrin ọlosa kan ti nwon npe ni Bandele Afolabi ti ọjọ ori rẹ nlo bi ogoji ọdun, ni awọn olopa ramu ti nwon si fi sun ẹsun wipe o ji taya ẹsẹ moto merin yọ, ti o je ti Ọgbeni Ọdejinmi, ọkan ninu awon olowo ati gbajumọ ilu Otta.

Awon ese moto na je ti ogbeni Odejinmi ti moto akeru rẹ kan ṣeṣi ṣe jamba lona Iẹjon Ijoko. Awon ẹsẹ moto na ni Bandele ko irinṣe lo tu, lojo 27th osu June 1959.

Adajo ye 'ejọ rẹ siwaju, sugbon ki nwon to gba iduro fun ki o lo wa onidaro wa, ti yio duro adọjọ ponun fun u ki nwon to gba iduro.

Lọjọ Alamisi to kọja lo yi ni nwon tun ko si ẹwọn rẹ. E o ma gbọ bi nwon ba ti tunṣe ẹjọ na si.

## EGBE ACTION GROUP FARAMỌ IMỌRAN WỌN



Ipade igbimo ti ijoba Liberia Ijoba Ghana ati Ijoba Guinea ṣe laipẹ yi, Oloye Enahoro sọ wipe ẹgbẹ Action Group fi ara mo irepo larin gbogbo awon ilu ti o mbẹ larin agbegbe Iwo-orun ilẹ Afrika.

## Itan Awon Omoba Meje.

(APA 2)

Omoba Alara okunrin dide lati lo sọ awon omoba na. Bi omoba na ti jade kuro nile, beni o pade Kurekure kan, o ni ki omoba Alara fun on ni onje ni toripe, o di ijeta ti on fi jeun gbehin.

Ọmọ Alara dahun pe, "Emi si ọ, iru emi ni yio ba iru are jeun papọ, o si fa ida rẹ yọ lati pa Kurekure na, sugbon ki o to fa ida yọ tan, o ti bẹ sinu igbo o si ti salo. Ni omo Alara ba kọri si ile ọba Olọfin.

Nigbati oba na gbọ pe omo Alara ni, o tun fi ye wipe, nkan ti o fe se yi, bi o ba kuna re, pipa ni on yio pa: omo Alara dahun pe fun ife ti on ni si omoba Olọfin, bi on ba titori re ku o tẹ on lọrun. Ọba si mu omo Alara lọ si ọdọ awon omoba meje na wipe alejo nyin niyi e jeki o sun nihin.

Gegebi enyin na ti mo wipe bi ilẹ ba ti su ni gbogbo omoba ma nsun. Nigbati ilẹ ti su, ni omoba Alara ti sun ti o si nhanrun, ko si mọ akoko ti awon omo Olọfin lo si ode ijo. Ni ọjọ keji, Olofin paṣẹ ki a bẹ lori. Ọmo Ajero tun dide wipe on nlo sọ awon omo Olofin meje na, bi nwon ba pa on nitori won, on fi ara mo. Bakanna gegebi ti omọ Alara ni nwon bẹ lori.

Nigbati o se ni Akanbi ọmọ Orongun ile Ila dide, o si mura lati lo mọ ibiti awon omo Olofin ti lọ njo. Ki o to lọ, o lọ ye Ifa wo, Ifa si kilo fun pe ko gbodọ ṣe ahun, lo ba bọ soju ona, o kọri si ọna Ile-Ifẹ.

Bi o ti nlọ loju ona, be lo pade Kurekure, o toro onjẹ lowo Akanbi omo Orongun ile Ila pe ki o fun on l'onjẹ. E ma ka iwe irohin Eleti-ọfẹ, ki ẹ si gbọ gegebi Akanbi ti ṣe mọ ibiti nwon gbe nlo jo. Lọsẹ ti o mbọ, e o gbọ kutupu ọrọ.

## NWON GBA ETI KAN, O FI SAN POUN MEJI

ENUGU. Omọkunrin kan ti o nje sidney ti o mbẹ lẹnu iṣẹ Ijoba, ni agbọ wipe on pelu obinrin adelebo kan woya ija ni fili-de-fili, awọn ọlọpa sọ wipe sidney lu obinrin na pupọ o si gba ni eti kan tobe ti eti na fere di.

Adajo sọ fun okunrin na pe iru iwo ti o mbẹ lenu ise oba kini eto re lati ma ba obinrin woya ija gegebi eni wipe okunrin elegbe re ni iwo mbaja.

Nitori eyi, o ti jebi obinrin na, ki o lo san poun meji si apo ijoba, bi o ko ba si ri poun meji san ki o lo gbewọ o su kan.





Buy the Railway PUBLIC TIME TABLE at 3d from your STATIONMASTER

Travel by TRAIN and RELAX

# LAGOS RACE CLUB

## August Meeting 1959.

## Sautrday 1st, 8th, 15th, 22nd & 29th August 1959.

### FIRST DAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Ten Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE NO. 2 | Ten Furlongs Handicap Bottom Division | 3.30 p.m. |
| RACE NO. 3 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4,00 p,m. |
| RACE NO 4 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.30 p.m. |
| RACE NO 5 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5.00 p.m |
| RACE NO. 6 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5.30 p.m. |
| RACE NO 7 | Eight Furlongs Handicap Top Division | 6.00 p.m |

### SECOND DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO 1 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO 4 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4. 15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 5.45 p.m. |
| RACE NO. 8 | Five Furlongs Handicap Top Division | 6.15 p.m |

### THIRD DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45p.m. |
| RACE NO. 2 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE NO 6 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE No 7 | POLO SCURRY | 5.45 p.m |
| RACE NO. 8 | THE OTUNBA PAYNE CHALLENGE CUP Ten Furlongs Handicap | 6.15 p.m. |

### FOURT HDAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE NO. 2 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 30 p.m. |
| RACE NO. 3 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 4. 00 p.m. |
| RACE NO 4 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4- 30 p.m, |
| RACE NO. 5 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 5. 00 p.m. |
| RACE NO 6 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 5.30 p.m. |
| RACE NO 7 | Eight Furlongs Handicap Top Division | 6. 00 p.m. |

### FIFTH DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE No. 3 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | POLO SCURRY | 5.45 p.m. |
| RACE NO 8 | THE COMMONWEALTH STAKES Twelve Furlongs | 6.15 p.m. |




Ra

Buredi



TI O GBADUN JULỌ TO SI NFUN NI LOKUN INU ATI ILERA

**BUREDI**

**"DE FACTO"**

TI O

LOKIKI FUN AJẸ GBADUN RẸ.


### WHY NCNC IS WORRIED

Dr. Azikiwe leader and life President of the N.C.N.C is worried, among other things that brought h's mission to America is the problem to the forth-coming general election.

The Television proget which was announced to the public was not sufficient for a Premier to worry about so long that there is a Minister in the Cabinet who is holding responsibility for such Portfolio.

Dr. Azikiwe has many obstacles to face in regards to the present political situations.

(To be contd)


# E Ma Ka

IWE IROHIN ELETI-ỌFẸ L'ỌSẸSẸ

O KUN FUN IROHIN ALADUN


Printed & Published by The Union Printing And Publishing Company 28 Kosọkọ Street P.O. Box 467 Lagos, Phone 23370